# OGUN DE BODE, O KU OMO ENITI O DURO!

Drink Coca-Cola
SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

U. T. C.
SERVES
YOU
WELL

VOL. No. VIII 492. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, NOVEMBER 3, 1956. KOBO MEJI (2d.)

## Ogun Keta Bere Nile Egypt

Ogun ti awọn Israẹli ti gbe ti ilu Egypt lati nkan bi ọjọ mẹta sẹhin ti bẹrẹ si bi Ige ati Adubi nisisiyi.

Nigbati ija ogun na bẹrẹ larin awọn ilu mejeji, Israẹli ati Egypt, awọn Olotu Ijọba Gẹsi ati Faranse fi ohun ṣ'ọkan ransẹ si awọn onija mejeji wipe, Ọgafa! ki nwọn da'wọ ija na duro, ki nwọn si ko ọmọ ogun wọn jinna si Itọ odo Suez niwọn ibusọ mẹwa larin wakati mẹrinlelogun.

Bi awọn ba kọ lati ṣe bẹ, awọn yio fi agbara la wọn ni'ja nitori idiwọ ti ija nwọn da silẹ lori Itọ odo Suez ti o jẹ ọna fun Ọkọ-oju-omi ti gbogbo agbaiye.

Awọn ara Egypt sọ wipe ohun ti o mu Gẹsi ati Faranse fẹ da si ija na ni ki nwọn le ri aye ṣe ifẹ inu wọn nitoripe awọn ti yọwọ wọn kuro ninu itọju Itọ Odo Suez ti iṣe ohun aj'ogunba fun ilẹ awọn Egypt.

Awọn ilu Amẹrika ati Russia sọ wipe ki ẹnikẹni maṣe fi agbara da si ija Israẹli pẹlu Egypt ṣugbọn Gẹsi ati Faranse ti bẹrẹ si lọ do si eti Itọ odo Suez nilu Egypt.

Ohun ti a tun gbọ laipẹ yi ni pe ọkọ ofurufu Gẹsi ti bẹrẹ si ju afọnja sibudogun awọn Egypt.

Ogun kẹta de!

THE NATIONAL BANK

Of Nigeria Limited

Ile ifi Owo pamọsi yi.
Nfi ọna owo han ọnia
Bi o ba fẹ jẹ onişowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna to dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti a nta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina, Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU OYINBO :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Anthony Eden



Ẹniti a nwo yi ni Ọgbẹni Sir Anthony Eden, ti o nṣe Prime Minister ilu Oyinbo Gẹsi, on ni ẹniti o fi iwe ransẹ si awọn ara ilẹ Egypt ati ọmọ Israẹli wipe, nipa ija ti awọn mejeji mba ara wọn ja, on fun wọn ni wakati mẹrinlelogun ki nwọn tuka kuro nidi ija na.

Bi nwọn ko ba fi kuro nidi ija na, ohunkohun ti awọn ba ri ni ohun ija ti o fi le jẹki awọn mejeji tuka ni awọn yio lo lati fi pari ija na kiakia.

Ọlọla Anthony Eden pari ọrọ rẹ s'ori wipe Igbin ni awa Gẹsi, ako ni fi ẹun le igi ki a ma gun" Ohun ti a ba wipe ao ṣe, a nilati ṣe nkanna.

A ṣe irohin ogun ti Israẹli ati Egypt nja na si apakan Iwe Irohin wa yi.



AWOGBA
Omode fun
Girl, Eyi,
Hiha-akin,
Orere.
Ra Tire Ni
Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare
Okebola,
Ibadan.
116, Great
Bridge St
LAGOS

TO CLEAR
Gents Suede Court Sho'
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at:-
A. B. AKINYẸMI
10A Moloney Bridge St
LAGOS.

## Ejo N'gboro



Ẹniti a awo yi ni Ologbe Ọgbẹni Herbert Macaulay C.E. On lo da ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ni ọdun 1923, Iṣẹ Wọdle-wọdle ni iṣẹ rẹ. O si ti ṣe iṣẹ akọwe agba nile iṣẹ Sẹkitari nilu Eko ri, eyi lo jẹki o ri pupọ ninu awọn aṣiri ijọba ilẹ Nigeria.

Nigbati o bẹrẹ iṣẹ iṣelu lo da iwe irohin kan silẹ ti a npe ni Lagos Daily News.

O ṣ'alaisi lẹhin ti o ti da ẹgbẹ Dẹmọ pomọ ẹgbẹ N.C.N.C. ti o si ba irin ajo ẹgbẹ na de ilu Kano, ki ailera ara to da pada wa'le.

Suore, Suore o,


## FUN ARUN GEHIN-GEHIN
## Dan Egbogi Yi Wo



Bi arun gehingehin ba nyọ ọ lenu lasiko igbati o bẹrẹ tabi ti o nse nkan miran irora yio ma bẹ fun oluwa rẹ bi a ba si wadi rẹ ao ri pe ohun ti o fa a mbẹ lara Kidinrin tabi Ọlọ-inu, iṣẹ wọn ni lati tu gbogbo ororo ti ko dara kuro ninu ara ṣugbọn awọn Kidirin nwọnyi ko nsiṣẹ wọn daradara nigbamiran. Nitorina ẹhin ti o ndun ọ le jẹ ikilọ wipe Ọlọ-inu rẹ nfẹ iranlọwọ.

Egbogi ti o daju ti o le siṣẹ yi ni DE WITT'S o nfọ idọti ara ẹni kuro o si ntu esua lara gbogbo awọn ti o ti nlo egbogi yi kakiri aiye lo ti nrohin rẹ.

Bi iwọ ba ka diẹ ninu iwe ti awọn ti o lo egbogi yi ti o siṣe iwosan fun nipa ẹhin didun iwọ yio mọ daju wipe bakanna ni yio ma wo arun gẹhin-gẹhin tirẹ san Ese ti iwọ ko dan wo fun irora tirẹ boya yio jẹ ohun ti o ba ọ lara mu

Bere ni Ṣọbu ti a nta egbogi.

A ṣe egbogi DE WITT'S nipataki fun arun GẸHIN-GẸHIN IGBA-ROKO, IWORA, ARUNGUN LAKUREGBE



Idaloju wa ni wipe egbogi DE-WITT'S je eyiti a ṣe tonitoni ti ko si idọti kan lara rẹ.

**DE WITT'S PILLS**
**for Kidney and Bladder Troubles**


Gegele l'o bi gegele, Koto l'o bi koto, ojo ro si koto, inu mbi Gegele. (Owe)


## Iwo le fi sile meji-abo (2/6)

## s'ere

## Sugbon ki ise Egbedogbon Poun (£5.000)

## Ra tikiti Orire Ijoba Iwo-Orun loni ki o to tan.

## Apapo owo ti ao pin je Egbarun Poun.

## £10,000

## National Bank Njere Lati Odun Kefa

Ọgbẹni Woolmer, ti o nṣe Accountant ti ijọba Gẹsi gba tati ilu Oyinbo wa wipe, ki o wa ṣe ofin toto gbogbo bi wọn ti ṣe nawo, ati bi nwọn ti ṣe fi owo si ninu African Continental Bank ati nigbati o si ṣe ofin toto Banki na tan, ogbọ wipe nwọn kuna, nwọn ko si ṣe ẹtọ.

Ṣugbọn gẹgẹbi on ti gbọ wipe iru ẹsẹ ti National Bank gbe ni Continental Bank gbe. Eyi lo mu on lati lọ ṣe ofin toto National Bank.

Iyalẹnu lo jẹ fun Accountant na nigbati o de National Bank, ko si irẹjẹ, ko si mọnọfiki.

Lọdun 1950 ni nwọn bẹrẹ ṣiṣi Banki na, lọdun na ere ẹgba a mẹta ni nwọn jẹ. Nigbati o si di ọdun 1955 apapọ gbogbo ere ti nwọn jẹ lati ọdun 1950-1955 jẹ £55,000. Ọpọlọpọ ile awọn Oyinbo onisowo l'o ni ọwọ ninu Banki na nisisiyi.

## Bale Ilu Ejidongari Fẹ Kito

BODE-SADU. A gbọ irohin wipe Alufa Abudu Kadiri Anidu ti o nṣe Balẹ ilu Ejidongari salọ kuro ni abule nigbati rogbodiyan bẹ silẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ ilẹ Hausa ati awọn ọmọ ẹgbẹ Ilọrin Talaka Parapọ.

Nigbati Saki ọba Ilorin gbọ wipe Balẹ Ejidongari fi ẹsẹ fẹ ẹ, o yan awọn enia sode wipe ki nwọn lọ wa Balẹ na.

Ninu rogbodiyan to ṣelẹ na awọn enia meji ni a gbọ wipe uwọn fi ara ṣeṣe, ti nwọn si gbe lọ sile Alaisan fun itọju.

Ọwọ ọlọpa koiti tẹ eyikeyi ninu awọn onija na, nwọn ṣi wa lẹnu iwadi ọrọ.

## Hitler ti ku aku fon!

Ijọba Gẹsi ṣe abere ọrọ lọwọ awọn Jamani wipe, nibo ni Hitler gbe lọ ti nwọn ko fi ri mu lasiko ogun?

Ijọba Jamani dahun wipe, bi awọn ba gbe ẹnu le ọrọ na wipe o ku tabi koku ko ni tẹ awọn Gẹsi lọrun ki awọn Gẹsi bere lọwọ ijoye kan ti a npe ni Hinze Linge, on ni ijoye ti o ntọju ile ti Hitler ngbe lasiko ogun, Ọgbẹni na koiti ku, on ni ẹniti o ni lati mọ ibiti Hitler gbe gba lọ nitori on ni iriju rẹ.

Awọn Gẹsi kọwe si Hinze Linge lati fun wọn ni idahun nipa Hitler. Asiko ti ọkunrin na da lati fun wọn ni idahun kikun koiti to, nigbati awọn ti nkan na ṣ'oju rẹ fesi wipe, ninu agbala afin Hitler ti a npe ni Baṣitẹsgadin. (Berchtesgarden) Hitler kọ yara kan si aja ilẹ, ati nigbati o gbọ pe ogun wọ ilu Jamani, ibẹ lo gbe pa ara rẹ si. o si da awọn loju gbangba pe Lord Hitler ko si mọ.

## Egbe awon omomeji.

EKO. Orişirişi ẹgbẹ ni nwọn ti da silẹ nilu Eko, bi ẹgbẹ Alagbafọ, ẹgbẹ Agbẹ, ẹgbẹ Alawo, ẹgbẹ Iranṣẹ, ẹgbẹ Alaṣọ, ẹgbẹ Awo, ẹgbẹ Onifa, Aladura, Elegungun, Alata, Onidiri, Aladiẹ Onişegun, Onişango, Eleyinlẹ, Oloriṣa-Oko ati orişirişi bawọnni ti a ko le ka tan.

Eyiti nwọn tun ṣeṣẹ da silẹ nisisiyi ni Ẹgbẹ awọn ọmọ Ileji tabi ọmọmeji gẹgẹbi Taiwo Kẹhinde.

Ṣugbọn boya awọn olotu ẹgbẹ na gbagbe lati fi ti awọn Ẹşu lẹhin Ibeji kun, gẹgẹbi Idowu, Alaba ati Idogbe.

Ibujoko ẹgbẹ na wa ni No. 15 Smith Street, Lagos. Alaga ẹgbẹ na, ni Ọgbẹni C. J. Martins, Ọgbẹni K. Işọla Labinjọ, ni akọwe ẹgbẹ na, ilẹ rẹ wa ni No. 2 Faji Street, Lagos. Telephone wọn ni 22852. Ni ile akọwe ẹgbẹ Ọgbẹni K. Işọla Labinjọ No. 2 Faji Street, Lagos ni awọn ibeji to ba fẹ wọ ẹgbẹ ti nf'oruko silẹ.

Awọn ti o ti f'orukọ silẹ le ni ọdunrun enia. (over 300 registered).



Okuta nla ṣele gbaragada-o-o,
Koroju, Koroju koro, Orişa nla
ti mi ewe agbọn riyẹriye,
Onile omu-tere nu, tere nu.

Aworan ti a nwo yi ni Mọlẹ ti o wa fun awọn Ẹyọ Ọlọgẹdẹ.

Ọjọ lọjọ agan nigba Ẹyọ Iya Oshodi ti awọn Ẹyọ Ọlọgẹdẹ pẹlu Ẹyọ Bamlaiye fẹ fi pẹki-ko-pẹki, ọpẹlọpẹ awọn agbagba to tete dide si ti nwọn fi kore e ija na.

Mọlẹ ajilu,
Mọlẹ Mọlaki.

154.

## Road Closure-Lagos-Abeokuta-Sunday 4th November.

The level crossing at mile 52 1/4 on the Lagos - Abeokuta road will be closed to all traffic from 7, 00 a.m. to 7. 00 p.m. on Sunday, 4th of November for railway repairs, alternative routes are Abeokuta via Ilaro to Papalanto or Abeokuta-Iperu-Shagamu.

153.

## Municipal Elections : 15th January, 1957.

In view of statements which have appeared to the contrary it is announced that the Regulations for the Election of Councillors under the second Schedule of the Lagos Local Government Law, 1953, will provide for the following:-

(a) Each voter will be given as many ballot papers as there are councillors to be elected for the ward.

(b) There will be one ballot box in each polling station for each candidate. Each box will bear the candidate's party symbol, if any, his name and his photograph.

(c) Each voter may cast one vote (and one only) for each of the candidates of his choice by placing one ballot paper in each of the appropriate boxes.

Complete secrecy of the ballot, therefore, will be preserved as in the 1953 Municipal Elections.

# ELETI QFE

A-NHU-WQN KO SE WI L'EJQ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
25, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. VIII. NO. 452 LAGOS, SATURDAY NOV, 3. 1956.


## K'a Fi Owo We'wo

Ni qwq fi nmq, ni owe awqn Yoruba ti a ba l'aiye, ako fẹ lati da si qrq ti awqn ijq Alatako inu Igbimq As'ofin Ijqba Iwq-orun nsq l'ori qrq Ominira fun ipinlẹ Iwq-Orun, eyiti Oyinbo akqwe agba tilu Oyinbo ṣe ikede rẹ wipe gẹgẹbi eto ti ijqba Iwq-orun, tabi Oloye Qlqla Qbafẹmi Awolqwq pẹlu awqn isqngbe rẹ ti ṣe silẹ fun ijqba ominira ni ipinlẹ na, ni eyiti ijqba Gẹsi ko gbagbe, ati pe awqn si ti mura lati yqnda ominira fun ijqba Iwq-Orun tabi eyikeyi ti o ba tun fẹ ominira ninu awqn ipinlẹ ti o ku nilẹ Nigeria.

Eyiti awqn ijq Alatako inu igbimq Iwq-Orun iba fi maa ṣe eto pẹlu ijqba, eto ti yio mu ifqkanbalẹ wa, ti gbogbo awqn enia ipinlẹ Iwq-Orun yio fi ri igbadun ijqba ominira, nṣe ni nwqn fi ẹtẹ silẹ ti nwqn npa lapalapa. O yẹ ki awqn ẹgbẹ Alakukq (N.C.N.C.) mq wipe ejo ti o ti ku ni qrq ti ominira fun ipinlẹ ijqba Iwq-Orun, owere l'o ku ti nwqn nja.

Nitorina, a fi wosika wa yi kesi awqn Olotu tabi awqn akonijẹ ẹgbẹ Oṣe'lu ti o jẹ ijq Alatako ninu Igbimq Ijqba ipinlẹ Iwq-Orun wipe ki nwqn ṣe ironu piwada bi qrq onigbagbq, ki nwqn f'aramq Ijqba ki ohun gbogbo le ma lq dede gẹgẹbi ipin'hun wqn pẹlu awqn enia ti o dibo yan wqn si aye na.

Bi a ba fi qwq wẹ'wq, qwq yio mq.

## Eran elese mefa

Lqdun 1936 nigbati adiẹ ban pamq ẹlẹsẹ mẹrin ni adugbo Oluwqle, nṣe ni gbogbo enia nrq girigiri lq lati wo iru adiẹ na, awqn ara Oluwqle papaa sq wipe, ẹiyẹ awodi kan lo ngbe qmq adiẹ na lq ki o to bq silẹ, o ti di oku.

Nigbati o si di qdun 1940 nwqn ni ẹran kan bimq ẹlẹsẹ mẹfa ni Lafiaji, bakanna ni gbogbo enia nrq giri-giri lq sibi ile Qgbẹni Martins, dudu ni ẹran na, ṣugbqn ogede gede ha, ha, ha lo pa ẹran na.

Eyi ti a tun ri gbq ni ẹran Agutan kan ti nwqn bi ni ẹlẹsẹ mẹfa, dudu ni ẹran na, ẹsẹ mẹrin dudu meji funfun.

A gbq pe ẹran na ko ku rara nwqn mu lq sile awqn ẹranko fun itqju, nibiti gbogbo enia yio ma wa fi ṣe-ran wo ni Zoo ti Accra University.


## Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials

PLEASE CONSULT :

# Okunowo Brothers

63 Massey Street, (Faji Market)
LAGOS, NIGERIA.
The house where Courtesy & Satisfation are Guaranteed


## Oko Oba Obinrin Se Ojo Ibi



Aworan ti ẹ nwo yi ni ti Qlqlajulq Ẹni-qla, qkq qba obinrin tilu Oyinbo Gẹsi ti a npe ni Duke of Edinburgh lo dagba di ẹni qdun marun-din-logoji lasiko ti o lq bẹ ilu Sweden wo, pẹlu iyawo rẹ Qba Gẹsi.

Ninu ilu Sweden ni nwqn wa nigbati awqn qmqba meji lq ba wqn ninu qkq igbaja kan ti a npe ni yacht Britania Ibẹ ni Qkq qba ti se ase qjq ibi rẹ.

Qkq qba yi ngboro lqdun yi lati rin irin ajo kakiri agbaiye. Yio wqkq lori omi, lori ilẹ ati lofurufu, gbogbo irin ajo rẹ yio jina, yio fẹrẹ to qkẹ meji ibusq.

On ni yio ṣi ibiti nwqn nfe ṣere Olympic nilu Melbourne lqjq 22nd oṣu November 1956. Bi o ba kuro nibẹ yio de awqn ilu nwqnyi:-

Tristan da Cunha, St. Helena, Ascension, Australia, New Zealand on nikan ṣoṣo ni yio lq, iyawo rẹ ko ni ba lq.

## Esin oro nile Yoruba---Owe

1. A ko mbinu ori, ki afi fila de idi.
2. Gbi nisu si, gbi li akaṣu, igbẹnu Aganran ni igbẹnu ekute ile.
3. Oalle ni lqwq, bẹni alejo di si ẹru.
4. Ibiti o wu ẹfufu lẹlẹ lo ndari igbẹ si, ibiti owu olowo eni, lo nran ni lq.
5. Daran-daran lẹiyẹ ti o nmu qsan.
6. Qmq ti Gambari bi, okun ni yio ran.
7. Esuru se aṣeju, o tẹ lqwq Oniyan
8. Agbalagba to ba fẹran rikisi ninu ahoro ile lo ngbe.
9. Bi a ba mba qmqde jẹ Iṣu l'oko, gongo imu lo ma nwo ni.
10. Abata takete, bi eni wipe ko ba odo tan.
11. Fija fun Qlqrun jẹ, ki o fqwq l'ẹran.
12. Ile li a ti nko ẹṣq re ode.

Tijani O, Amuṣan

St. David's School

Gbqgan

## Olosa Kan Ge Olopa Leti Je

ACCRA. Okunrin Aganyin kan lo lo jale ti owo Olopa si te, Olosa na nfe gba ara re sile kuro lowo olopa, sugbon nitoripe Olopa na lagbara, okunrin Olosa na ko le bo lowo olopa yi.

Nigbati o ripe owo ati ipa on ko le ka olopa na, lo ba di mo, o ge Olopa na leti je.

Ejo ti wipe o ge Olopa leti je ni awon koko ba ro Adajo so pe o gboju-gbaya, o ge opa oba leti je ki o yara lo si ewon osu mesan,

## Ta L'ogo Julo ?

Nigba kan Awon omo iya meta kan wa ti oruko won nje Agodiran, Gongosu ati Agobowale, Iya awon meteta yi a si maje Agojuwonlo.

Ni ojo kan won gbo Iro lati ilu okere pe ogun nla nbo wa si ilu won laipe. Gbogbo ilu arogidi pe ogun de! gbogbo ilu si mura ogun sile gidigidi, Oni ibon gbe ibon, Ida ati ada lati fi lo ja Ogun na.

Nigbati ogun naku owuro ojo keji, awon ara ilu ko sun nitori ki ogun ma ba wo ilu ni oru. Nigbati o di dede agogo mefa owuro ojo ogun na ni awon omo iya yi ba lo kuro nilu, Agodiran lo so pe ki awon le le won pada ki awon mase de ilu awon mo

Nigbati won rin bi ibuso meta (three miles) si ilu, ni okan so pe on yio sun si oju ona ti won bade won aso pe on Agodiran ti ku ni, ekeji Gongosu na bo si eti igbe leba ibiti Agodiran dubule si eyi eketa gun ori igi lo o si dake sibe minimini.

Nigbati ogun to nbo wa si ilu won de odo Agodiran ni bi to dubule si, okan ninu awon Ologun yi na ni kumo ni agbari o si pa, bi won ti fe wo oku Agodiran sigbe ni Gongosu ba so pe e mase jeki eje ta si mi lara o, ni awon Ologun ba so pe awa ko ti e ri o tele, won pa on na pelu, o wa ku Agobowale lori igi ti enikan ko mo pe, o wa nibe.

Bi awon Ologun yi ti rin bi ese bata mewa si idi igi ni Agobowale ba kigbe soke pe Ah! eo tile ri mi, o dabo o, beni won ba so kumo si Agobowale on na si ku pelu won.

E jowo, enyin okawe, mo fe mo eni to go ju ninu awon omo iya meteta yi.

Mo dupe aye ti Olotu gba mi lati so itan kekere yi o

Emi ni
Rahman A. Afolayan
(Alias Golden boy)
S.H. School

## Owo te elewon to salo.

ILORIN. Okunrin kan ti a npe ni Adebayo Ayinla ti o lo ji won ni tolotolo gbe, ti owo olopa si te e, Alalikali sa konko ewon mo lara.

Ninu ewon ni okunrin odaran elewon yi wa ti o tun ba ara re ro wipe ki on sa salo ni ohun ti o ye on, Kawi-kafo, okunrin na s'ogbon-sogbon e ri aye salo.

Gere ti o salo tan, ni awon gbe ibon ti awon nwa kiri. Owo won si te okunrin na nibiti o nfe paro aso ewon re, ni awon ba tun da pada si ogba ewon, ninu ose ti a o bo si yi ni awon olopa yio mu oro re lo fi sun Alkali ni Ilorin.


## CARSON PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENT:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 - 28 BALOGUN STREET, LAGOS.


E Ma Ka Iwe Irohin Eleti--Ofe - Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Iwe Irohin Aladun Yi.



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon omo ile Nigeria ti o nlo ba won se ere Olympic nilu Melbourne ni osu November 22nd, 1956.

Awon enia nwonyi ti wo oko ofurufu lo si ibi ere na nisisiyi. Oko Oba Obinrin Duke of Edingburgh ni yio si ibi ere na. Adura wa ni pe ki Olorun jeki nwon ba orire pada wa sile.

## Edekoyede Larin Gbegi Ati Gbebo

Lọjọ kan, Gbẹbọ nsọ fun awọn ijọ tirẹ wipe, Ẹ maṣe bẹru mọ, ohun ti a nfẹ ti tẹ wa lọwọ, ominira to daju ti de fun ilẹ Yoruba, tabi kilopo. Gbogbo wọn si nkọrin bayi pe, Adupẹ t'Ọlọrun ko pa wa lẹkun, adupẹ.

Gbegi – Ha ha ha, he he he, hi hi hi, O gbele o, ẹrin pa mi titi, mo yi ṣubu gbiri-gbiri. Ẹ ha le ma tan ara nyin jẹ bayi ndan? tabi ẹnyin ko mọ wipe, gedegbe ni Eko wa, Iru wa, ogiri wa ni ilu Eko.

Gbẹbọ – Bi ẹnyin ba jẹ omugọ, awọn oyinbo ti o ntọ wa ha tun le jẹ omugọ? Amọ ha le wi fun Amọkoko wipe ko mọ en dara-dara-bi? Ọna ti Eko fi jẹ Iru wa, ogiri wa ẹo ṣa la idi rẹ fun aiye gbọ. Yala ẹfẹ tabi ẹ ko fẹ, ominira yio kan wa lara ni Januari 1957.

Gbegi – Iṣọkan ilẹ Nigeria ni a fẹ, bi awa gbegi ko ba si lohun si, awọn oyinbo ko ni fun yin ni ominira, ati wipe gedegbe ni ilu Eko ni lati wa.

Gbẹbọ – Ṣe ẹniti o gọ ni a fi ndi Elekuru. Gedegbe li Eko wa, abọ gedegbe na niyi, ṣe nitori ki awọn ajeji enia le gba ilu Eko ni nwọn ṣe nkọ yin pe gedegbe ni ki Eko wa, nwọn gba ile nyin, nwọn gba ilẹ pẹlu. Njẹ nigbati ilu Eko ṣi wa pẹlu ilẹ Yoruba yoku ti nwọn sọ wipe nwọn nfẹ wọ'le nṣe kọ ni Awolọwọ paṣẹ pe nwọn ko gbọdọ wo ile ẹnikan?

Gbegi — Ori ni ilu Eko jẹ fun gbogbo ilẹ Nigeria, nitorina ko nṣe ilu ẹnikan, ni p a t a k i, gbogbo wa lo jijọ ni, Hausa wa nibẹ, Ibo, wa nibẹ, ọna wo lo fi wa jẹ ti Yoruba nikan?.

Gbẹbọ — Isọkusọ li eyiti o nsọ yẹn, nigbati Aṣipa ntẹ Eko, nibo ni Ibo wa? Tabi nigbati Akintoye lọ mu oyinbo bọ lati Okun, nibo ni Ibo wa? Lọdun 1941, nigbati oju nyin koiti la, ni Gomina Lugadi ṣe ofin kan ti a npe ni Amaga eyiti o ṣ i n a fun nyin lati ma wa si Eko, ki oju nyin b le la. Nigbana ti ẹ si de si ilu Eko, mo ṣebi iṣẹ Bọyi-bọyi ni ẹ nṣe lọdọ wa ti a si nran nyin lọ silewe.

Gbegi — Awọn igbimọ wa yio ṣe Ipade lati Aba de Enugu ati lati Pọta de Kalaba, ao fi gbogbo agbara wa ja ijakadi ki a le gba ilu Eko lọwọ nyin, ao ya owo ni Kọgila Banki ao si gba gbogbo ilu Eko fun ara wa, ni oripe ko si ẹnikan ti o le sọ pe ọmọ Eko yi ni on. Iru wa, ogiri wa ni Eko

Gbẹbọ — Ilu to ba wa. ti ko ni olori, egbe ni fun awọn enia ilu na. Gbogbo nkan ti Ọlọrun nkan ti Ọlọrun da lo ni olori tabi ọba, avafi awọn gbegi.

B'awa lo ju nyin lọ, b'ẹnyin lo ju wa lọ, ipade di'badan.



SHETIMA KASHIM

Ẹniti a nwo yi ni Malam Shetima Kashim, ẹon li Hausa ti a ran lọ si ipade igbimọ kan ti o ṣelẹ ni Cambridge nilu Oyinbo ti nwọn si fun laye lati sọrọ sinu ẹrọ N. B. S. Aworan rẹ ni a nwo yi nigbati o nsọrọ ni ede Hausa,

## Mo Gbadun Siga Pirate




PIRATE

Ni Siga To Dara

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**Ọ M Ọ R E L A B A B Y M I X T U R E**

*(SILE MEJ: ABO 2/6d. FUN GO KAN)*

O wa Lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS

**Poppy Day Saturday 10th Nov.**

**PLEASE GIVE GENEROUSLY.**

## Israeli Gbogun Ti Ile Egypt.

A gbọ irohin wipe ogun awọn ọmọ Israeli kọlu ogun ilẹ Egypt. Nwọn pade ija na ni afoni - foji oke Sinai, nibiti oju ọna tero kan gbe wa, tọ'un tosi lo padanu, ṣugbọn ti awọn ọmọ Israẹli lo pọju.

Ọgbẹni Anthony Eden ti o nṣe Prime Minister ti ilu Oyinbo ranṣẹ si awọn ara Egypt ati awọn ọmọ Israẹli pe, on fun wọn ni wakati merinlelogun ki olukuluku nwọn da ogun duro, bi bẹkọ, Gẹsi ati Faranse yio yọ si wọn lojiji pẹlu awọn ohun ija ti nwọn ba ri lati fi da ogun buburu yi duro.

A gbọ pe, ogun awọn ọmọ Israẹli ti sunmọ eti ilẹ Egypt pupọ, nwọn si ti bẹrẹ si fi awọn ọkọ ofurufu wọn ko awọn ọmọ ogun sọkalẹ si odi keji odo ilẹ Egypt Antony Eden sọ fun awọn igbimọ wipe ijọgbọn patapata ni ogun na yio da silẹ ayafi bi a ba tete pana ọtẹ na, bi bẹkọ ijọngbọn ni yio da silẹ fun wa ni Ebute Suez.

Ọgagun awọn Ọlọkọ oju omi nilu Gẹsi, ti ṣe ikede ikilọ wipe, gbogbo ọkọ ti o nlọ si India, Fiji, Australia ati East Afrika, ki nwọn maṣe gba ebute Suez kọja ki nwọn lọ gba itomiran.

Nigbati ilẹ mọ ogun ilẹ Egypt ti kọja si odikeji ebute Suez, awọn ọmọ Isrẹli si ti kọja si agbegbe ilẹ Egypt. Ibiti nwọn kọkọ pade ija ni ilu kan ti a npe ni Rasel Naguet.

## Pakilaaso pa Akilaja je

Nigba lailai, nile Ijaiye, eṣo kan wa ni orita ilu Ijaiye ti a npe ni Pakilaṣo. Kurumi Arẹ Ijaiye lo fẹ eṣu na sibẹ, bi ile ba si ti ṣu tan, ko si eniti o le gba ojude eṣu na kọja.

Lasiko na, ọkunrin kan ijoye wa nile Ijaiye ti a npe ni Akilaja. Nṣe ni gbogbo enia mbẹru Akilaja, o si to ra ni ẹgba a ọkẹ lasiko ogun, on ni ẹniti o kọkọ jẹ oye Alapinni, ti o gburo pe Arọni kan wa lọna Ṣaki, bi Arọni na ti buru to, nṣe ni Akilaja fa a wọ ilu Ijaiye wa bi ẹni fa aja. Eyi na lo di owe ti nwọn npa loni wipe, bi ijimere ba foju kan Alapinni gbogbo ero inu rẹ yio pin.

Li ọjọ kan, Akinlaja ranṣẹ lo sọ fun Arẹ wipe ki o kilọ fun Eṣu rẹ wipe ki o fun on laye lorita Ijaiye, nitori on fẹ kọ ile kan sibẹ. Arẹ ranṣẹ pada wipe Pakilaṣo fun'ra rẹ leti ki o lọ ba a sọ. Ka ma fa ọrọ gun, Akilaja ni ki nwọn bẹrẹ si ile na ni kiko.

Bi nwọn ti fẹ kọ ile na tan Eṣu sọ fun wọn pe, nwọn ko gbọdọ tun wa mọ ile na mọ. Akilaja dira fun wọn, o ni ki nwọn ma ba ile na niṣo. Nwọn kọ ile na tan. Eṣu ko si yọ nwọn lẹnu mọ.

Nigbati o di ọjọ ti Akilaja nilati wa sun ninu ile na bi Akilaja ti wole, o ba Pakilaaṣo ti o joko dee, Akilaja ko tilẹ fẹ mọ pe ẹnikan mbẹ ni ijoko, o bẹrẹ si so ado mọ ara ile na kakiri. Pakilaaṣo nwo. O jẹ jijẹ, o mu mi mu, o sa sisa, o pa ọfọ, o pe ogede, nṣe ni Pakilaaṣo nwo.

Enikini kole sun, bẹni enikeji pẹlu, nigbati ilẹ nfẹ mọ, bẹni Akilaja bẹrẹ si t'ogbe, ibẹ ni Pakilaaṣo ba ti bẹ lori o si gbe ju si ikorita.

Awọn ti o tete ji ni idaji ti o nlọ si oko l'ori ori Akilaja nikorita, o di pẹ ntuka ni nwọn ba mu irohin lọ sọdọ Arẹ-ọna Kakanfo. Nigbana ni awọn onilu ogun fun Arẹ ba bẹrẹ si fi ilu kọrin bayi pe:—

Paki-la-aṣo-p'Akilaja-jẹ
Paki-la-aṣo-p'Akilaja-jẹ

## Awon Rosia nse aseju

LONDON. Awọn Gẹsi pe ara wọn jọ nwọn si ṣe'gbimọ lori iro ti nwọn gbọ nipa wipe awọn ara ilu Hungary nfẹ ki awọn Rọsia fun wọn ni ominira eyi ni tọtun-tosi wọn nfa mọ ara wọn lọwọ ti Rọsia fi ko awọn ohun ija ogun jọ, ti nwọn si lọ bẹrẹ si yọ awọn enia na lẹnu.

Ọgbẹni Gaitskel sọ wipe, iru iwa ti awọn Rọsia lọ hu nilu Hungary yi, jẹ iyalẹnu fun on nibiti Rọsia gbe laju de yi, lati ma fi ohun ija wahala awọn ara ilu ti ko mu ọkọ tabi ada dani lati ja. Ayafi bi awọn Rọsia ba yara ko ọmọ ogun wọn kuro nilu Hungary l'o dara julọ.

Lloyd dahun wipe, kini? awọn tilẹ tun gbọ wipe, awọn ọmọ ogun wọn ti nwọn ko wa si mbẹ nibẹ, nwọn ṣẹṣẹ tun ko awọn enia miran wa kun awọn ti o ti wa nibẹ ni ṣugbọn o da mi loju wipe gbogbo iru iwa ti awọn Rọsia nhu yi ni awa ti o nsọ ede Gẹsi ti nfojusi pẹlu awọn ti o mbẹ labẹ aṣia Gẹsi, gbogbo wa lo si nkanu fun awọn ara Hungary.

Nitori ọrọ yi, aṣoju ilu Hungary kan ti lọ si ile iṣẹ ẹgbẹ gbogbo agbaiye nilu New York, Amerika, lati fi ọro ẹjọ na sun. A si nreti eyiti awọn araiye

yio sọ nipa ọrọ yi, ki a to

ko gbogbo ọrọ na jọ fun

apero.



Eniti a nwo yi ni Dokita Ayikiwe, ti o nṣe Prime Minister ni ilẹ agbegbe Ila Orun, on ni ẹniti Sẹkitẹri agba nilu Oyinbo nse iwadi nipa rẹ ati Banki rẹ ti o da silẹ ti a npe African Continental Bank Ltd. Lati iwọn oṣu kan ti iwadi ọrọ na ti bẹrẹ, a kọ'ti fun laye lati sọrọ, ṣugbọn nisisiyi on ni ẹniti ọrọ kan ninu ọsẹ yi.

## Omo Adumila sina

OLOTU,

Jọwọ gba mi laye lati da si ọrọ obinrin afọju, aditi ati ayadi, ko le riran, ko le sọrọ, leti ko le gbọrọ, ti ọmọ rẹ si wa ku sẹhin odi, o wa ku ẹniti o le tufọ na un iya ọmọ na.

Loju temi ko si ẹniti o le tu ọfọ yi fun iya na iya na fun'ra rẹ ni yio mọ, nigbati ko ba gburo, bi o ti o ngburo, ti ko ri oniṣẹ bi o ti nri tẹlẹ, ara yio fu u. nipa bẹ yio mọ pe ohun kan ṣẹlẹ si ọmọ on.

Ṣugbọn itumọ ti ọmọ Adumila fun wa ni wipe owe ni on fi ọrọ na pa, bi ọro ba si jẹ bayi, ọmọ Adumila ṣina, nitoripe ko sọ wipe owe ni ọrọ na.

Nitoripe ko si eniti o le tufọ na, ati pe nigbati ọmọ Adumila paa ko ribi gbegba lo ba yi ọrọ na si owe. Ha! ọmọ Adumila, o si ti ṣina.

Emi ni
Braimọ Ogulutu

## ERE DOKITA NKRUMAH

A gbọ wipe ere ti a fi idẹ ṣe ni aworan Dọkita Kwame Nkrumah ni a o gbe si ọkankan Post Office nilu Accra fun iranti Ijọba ominira ti Dokita Nkrumah gba.

Ere na gun to iwọn ogun ẹsẹ, yio fi Dokita Nkrumah han ninu ẹwu awọn Hausa to wọ le ori awọtẹlẹ alapa kukuru pẹlu ṣokoto.

Ay'aworan ara ile Itali kan ti a npe ni Dokita Sergio Barbeski ati Agbegilere ara ilu na ni yio wa gbe ere na ka'lẹ nilu Accra, Gold Coast.

## Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos

# Sara-tori-Ọlọrun S'orire

Ere eşin sisa tabi tẹtẹ ti ijọba ilu Jamaica şe ninu oşu September 19 6, awọn ti o şe orire nilẹ Nigeria wa yi lo pọju. Awọn enia ti o şorire ati iye ti awọn jẹ niwọnyi:—

AWỌN TO JẸ £28: 11: 5d.
Temi dipe - Ilaro
Sara tori Ọlọrun - Lagos
One way - Agbor
Suffer me not - Benin
Onyemaechi - Onitsha
Shamsi Disu - Ikorodu
God know kupe - Ahoada

£24: 15: 3d. ẸNIKỌKAN
One - day - Enugu
Sendido - Lagos
Onye na chi ya - Makurdi
May God help - Lagos
Mary Brown - "
Lawrence Eyi ko gbe - Lagos
Simeon Anochie - Aba
All for God - "
Madamiro - Abeokuta
Chukuemeke - Lagos
O God help me - Aba
Right - Time - P. Harcourt
Chinyere Okeke - Lagos
Dui Sule - "

£97: 9: 10d. ẸNIKỌKAN
Mọşọbalaje - Lagos
Anene chi - Benin
Fracis Otobo - "
Help me God - Ebute metta
Spot Zik - Onitsha
Ireti - ọla - Ebute - metta
Mọrẹnikẹ-Ẹşọrun - Lagos
Little Brother - Lagos
God's will - Ilare
Odumare Gbebẹ - Lagos
Loko Amusu - Apapa
Salami Okun - Lagos
Ngosibia - Enugu
A. Slave - Onitsha
Grace Ozugbo - Warri
Monica E. Umunkwe - Lagos
Popoola Olageşin - Mushin.

## Maulvi M. A. Saqi left for Pakistan

Maulvi M. A. Saqi, H. A. Shahid, a Missionary of the Ahmadiyya Mission left for Pakistan on 29th October, 1956 after four years' strenuous service in the cause of Islam.

In addition to his missionary activities, Maulvi Saqi was Manager of the Fazl-i-Omar Ahmadiyya School, Lagos Assistant Editor of THE TRUTH and a regular broadcaster at the N. B. S.

Maulvi Saqi who was keenly interested in activities of the Muslim youth was a Patron of the Ahmadiyya Boys Club.

While on his way to Pakistan Maulvi Saqi hopes to stay in London for some time in the interest of THE TRUTH.

N. M. Naseem Saifi
Chief Ahmadiyya Muslim Missionary,
West Africa.


## Ogun Aran (Ejo Inu)




Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buburu ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran, bẹni o npa ẹyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6d. Owo-Ọkọ si jẹ 1/-.

THE ẸGBA TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.


# Ile egbe U. A. C. ni Ibadan



Ile daradara ti a nwo yi ni ile ti awọn ẹgbẹ Onişowo U. A. C. kọ si Ibadan, ninu ile yi ni awọn Alarina ijọba (Western Region Information Service) fi şe ibujoko, o si jẹ ọkan ninu awọn ile ti o milijọ ti o si dara gidigidi ni igboro Ibadan.



Aworan ti a nwo yi ni awọn ọmọ ilẹ wa nihin ti nwọn lọ danrawo pẹlu awọn ilu ajeji miran nilu Melbourne.


# WO AMI YI....

LYONS ICE CREAM

.... Eyi l'ofi han o wipe ibe l'o ti le ri Ap'orungbe atata ra (DELICIOUS ICE CREAM) Iwo o ri'gbadun owo re.



## IRIN AJO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ rin irin ajo, yala lọnu işẹ tabi fun faaji lọ si ibikibi ni apa ilẹ Nigeria, tabi lọ si apa ilẹ Iwọ-Orun Africa tabi lọ si ibikibi agbaiye.

WA BERE

Lọdọ awọn AMONA irin ajo yala lori omi, l'ofurufu tabi lori ilẹ ninu ọkọ Reluwe.

Jẹki a ba ọ şe gbogbo wahala rẹ nipa Iwe aşẹ fun irin ajo (Passports) Iwe Ọkọ-ilẹ (Tickets) aye ijoko si ati ifọkanbalẹ jamba (Insurance).

Ao ba ero Mẹka şeto Ọkọ pẹlu irọrun. Iranşẹ ni ajẹ fun ọ lo wa.

West African Travel Agency Co.,
9, Victoria Street, Box 581,
LAGOS PHONE 23237


Printed & Published for The ... printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone ...